Bibeli fun awon omode



# Okunrin ti oti odo Olorun wa

Ikosile gba owo: Edward Hughes

Ayaworan: Byron Unger; Lazarus

Olu'lo: E. Frischbutter; Sarah S., Alastair Paterson

Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu

Alakoso: Bible for Children
www.M1914.org

©2020 Bible for Children, Inc.
Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi, niwon igba ti o ko so di owo.

Li ojo kan ninu tempili, Alufa agba kan, ti nje Sakariah, nfi turari jona. Li ode, awon eniyan ngbadura. Lojiji, Sakariah beru.



Angeli kan to o wa. "Mase beru" owi fun. "Olorun ran mi. Iyawo re yio bi omokunrin kan. Pe oruko re ni Johannu.



Yio kun fun Emi mimo lati inu oyun wa. Yio yi awon Eniyan mi pada si Olorun”.



"Bawa s'oro, Sakariah." Oya awon eniyan towa lode lenu. Won ko mo wipe angeli Gabrieli t iwi fun Sakariah wipe ki yio le soro ...



... titi ojo ibi omo na nitoripe ko gba oro Olorun gbo. O ro wipe Iyawo re ti dagba ju eniti ole bi omo lo.



Ni Ile, Sakariah ko gbogbo ohun ti Angel wi fun. Oje iyalenu fun Elisabeti, Iyawo re. Won ti ngbadura lati ri omo bi. Nje ole sele bayii?





Laipe Elisabeti mo wipe omo nbo. O fiyin Fun Olorun. Li ojo kan, Ibatan Elisabeti, Maria, se abewo re. Maria pelu loyun omo.



Nigbati Maria wole de,
Ole omo so ninu Elisabeti.
Elisabeti kun fun Emi mimo.
Oni Idani loju wipe omo Maria gbodo je Jesu Kristi. Lapapo, awon Ibinrin meji wonyi fiyin f'olorun pelu ayo.



Elisabeti bi omo gegebi Ileri Olorun. “Pe oruko re ni Sakariah, gegebi Baba re,” awon Alufa lo so eyi. Sugbon Sakariah ranti ase Olorun.



"Rara o! Johannu
Li oruko Omo na."
Nigbati Sakariah
ko awon oro yi sile,
ahon re si lati so'ro.
O fiyin fun
Olorun.

Nigbati Johannu
dagba odabi Elija,
Eniyan Olorun nla.
Johannu so fun awon
Eniyan wipe Olugbala
nbo lati wa bukun
fun won.





Awon agba Ju korira Johannu nitoripe oni ki won "ronupiwada! Ki won mase da ese mo." Won ko fe gbo ohunkohun nipa ese won.

Awon miiran pe ni Johannu onitebomi nitori wipe o rin awon eniyan sinu omi ki won bale kedun fun ese won.



Li ojo kan, Jesu to Johannu wa lati se iribomi. "Iwo loye ki ote mi bomi," Johanu wi. Sugbon Jesu wi fun pe "Jeki ori be." Johannu si ribomi.



Lehin iribomi
Jesu, Johannu
ri Emi mimo
sokale s'ori
Jesu ni rir eiye
Adaba. Eyi ni ami
Olorun. Johannu
mo wipe Jesu
ni omo Olorun.
Johannu pe Jesu
li Odo-aguntan



Johannu mu opolopo Eniyan wa si odo Olorun. Sugbon Herodu, asebi ni, Mu Johannu osi fi sinu tubu. "Kiise ohun toto lati gba aya arakunrin re, Herodiasi gegebi aya a re," Johannu wifun Herodu.



Herodu mo wipe otito li eyi je. O mo wipe Iranse Olorun li Johannu nse,



eni otito and eni mimo. Sugbon ko fe dawo ese re duro. Johannu pelu ko le dekun lati ma soro si ese bo tile je wipe afi sinu tubu.

Herodu ni ayeye ojo ibi nla. Omobinrin Herodiasi jo fun. Eyi te Herodu l’orun.  Herodu se Ileri “Ole ni ohunkohun ti oba fe, titi de idaji Ijoba a mi”.





"Kini ki n bere fun" Omobinrin na ronu. Eni ibi Herodiasi, to korira Johannu so ohun ti yio bere. Oje kayefi!

“Fi ori Johannu onitebomi si ori apete fun mi,” omobinrin na wi fun Herodu. Inu re baje nitori ileri re, sugbon ogberaga lati yi pada.




"Ge ori Johannu, ki o gbe wa",
Herodu pase.
Awon omo ogun re gboran si lenu.

Pelu ibanuje okan, awon ore
Johannu sin oku Johannu,
iranse to gboju tosi
je olooto. Ise
iranse Johannu
ti pari. Boya
won mo wipe
Jesu yoo tu
won ninu, ninu
ibanuje won.



Okunrin ti oti odo Olorun wa

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

Maku ori kefa, Luku ori ikini ati iketa

"Iwole oro re funwa ni imole."
Orin Dafidi 119:130

Opin

Itan Bibeli yii so fun wa nipa Olorun iyanu wa t'oda wa ti osi fe ki amo ohun.

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese. Iku ni ere ese, sugbon Olorun feran re tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Bi o ba gbagbo ninu Jesu ti osi toro idariji ese re, Yi o se eyi! Yi o si wa gbe ninu re nisisiyi, iwo yio si gbe pelu re lailai.

Bi o ba gbagbo wipe
otito ni eyi, so fun Olorun wipe:
Jesu mi owon, Mo gbagbo wipe ire ni
Olorun, o di eniyan lati ku fun ese mi,
osi wa laaye sibe. Jowo wa sinu aye mi
ki osi dari ese mi jimi, ki emi ki oni aye
otun nisisiyi, ati ni ojo kan ki emi kole
wa pelu re titi lai. Ranmilowo lati gbo
tire ati lati je omo o re. Amin.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun
soro lojumo!
Johannu ori keta ese kerindinlogun.